# ABRAHAMU FI ISAAKI RUBỌ

**Gẹnẹsisi 22:1-18**

**ẸKỌ 11 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ẹ máṣe ka idanwò iná ti mbẹ larin nyin eyiti o de si nyin lati dan nyin wò bi ẹnipe ohun àjeji li o de bá nyin" (1 Peteru 4:12).**

**I Abrahamu ri Iyiiriwo Kikoro lati Ọwọ Ọlọrun**

1 A pa a laṣẹ fun Abrahamu lati fi Isaaki ru ẹbọ sisun, Gẹnẹsisi 22:1, 2

2 O gbọran lẹsẹ kan naa, o si dide ni owurọ ọjọ keji lati lọ si Oke Moria, Gẹnẹsisi 22:3; (Wo 1 Kronika 21:18-26; 2 Kronika 3:1 pẹlu).

3 O paṣẹ fun awọn ọmọ ọdọ rẹ lati duro de ipadabọ oun ati Isaaki, Gẹnẹsisi 22:4, 5; Heberu 11:17-19

**II A De Isaaki a si Gbe E Dubulẹ lori Pẹpẹ**

1 Baba ati ọmọ jumọ n lọ si oke irubọ, Gẹnẹsisi 22:6

2 Abrahamu fi asọtẹlẹ dahun pe, "Ọlọrun tikalarẹ ni yio pèse ọdọ-agutan" Gẹnẹsisi 22:8 (Wo 1 Kronika 21:18-26; 2 Kronika 3:1 pẹlu).

3 Abrahamu si to pẹpẹ, o to igi sori rẹ, o de Isaaki, o si dá a dubulẹ lori rẹ, Gẹnẹsisi 22:9

**III A Dá Ọwọ Abrahamu Duro**

1 Nigba ti o ti ṣe ohun gbogbo tán, Abrahamu gbé ọbẹ soke lati dumbu ọmọ rẹ, Gẹnẹsisi 22:10

2 Ohùn lati Ọrun wa wi pe, "Máṣe fọwọkàn ọmọde nì" Gẹnẹsisi 22:11, 12; Owe 9:10

3 Abrahamu rí agbo ti o fi ori há pantiri, o si fi i rubọ, Gẹnẹsisi 22:13, 14

**IV A fi Idi Majẹmu pẹlu Abrahamu Mulẹ**

1 Oluwa si sọrọ lẹẹkeji, O fi ara Rẹ bura, Gẹnẹsisi 22:15, 16; Heberu 6:17, 18

2 Ọlọrun fi idi ibukun ti a ti ṣeleri fun Abrahamu lati ipilẹṣẹ mulẹ, Gẹnẹsisi 22:17; 12:2

3 A fi idi ileri fun awọn orilẹ-ède mulẹ pẹlu, Gẹnẹsisi 22:18; 12:3

## ALAYE

**Iyiiríwo Abrahamu**

Nigba ti ẹni kan ba tọ Oluwa wa fun igbala ọkàn rẹ, oun a maa ri i gbà nigba ti o ba fi ara rẹ ji fun Oluwa patapata lai ku ohun kan. Yoo ṣe ileri lati sin Ọlọrun. Nigba ti o ba n wá isọdimimọ yoo sọ awọn ileri rẹ di ọ̀tun, yoo si fi ayé rẹ rubọ ju bẹẹ lọ fun Oluwa. Ọlọrun a maa fun wa ni awọn iriri Onigbagbọ́ wọnyii lori awọn ileri ti a ṣe fun Un. Oun a si maa fun wa ni awọn iriri naa ṣaaju imuṣẹ awọn ileri wa; ṣugbọn lai pẹ, akoko yoo de nigba ti a o beerè lọwọ wa lati mu awọn ileri ti a ti ṣe fun Ọlọrun ṣẹ.

Akoko de nigba ti Ọlọrun pe Abrahamu lati mu ileri ti o ti ṣe fun Ọlọrun ṣẹ. Iwe Mimọ́ wi pe, "Ọlọrun dan Abrahamu wò." Itumọ eyi ni pe Ọlọrun yiiri rẹ wò. Ọlọrun ki i dán eniyan wò lọna ti eṣu n gbà dán ni wò, ṣugbọn Ọlọrun a maa yiiri eniyan wò; A maa dán ifẹ ti o wà ninu ọkàn ọmọ eniyan wò. Ọlọrun wi pe "Mu ọmọ rẹ nisisiyi, Isaaki, ọmọ rẹ na kanṣoṣo, ti iwọ fẹ́, ki iwọ ki o si lọ si ilẹ Moria; ki o si fi i rubọ sisun nibẹ̀ lori ọkan ninu oke ti emi o sọ fun ọ." Mu ọmọ rẹ, eyi ti Mo ti fun ọ, Abrahamu, ki o si fi i rubọ si Mi. Má ṣe jẹ ki ifẹ ọmọ naa yà ọ́ nipá si Mi; Temi ni ọmọ naa pẹlu; Emi ni Mo fi i fun ọ, Mo si le beere rẹ̀ lọwọ rẹ.

Aṣẹ yii wá gẹgẹ bi manamana ti n kọ loju sanma. Abrahamu kò reti ohun ti o jọ bayii rárá. Oun ti duro fun ọ̀pọ̀ ọdun fun imuṣẹ ileri pe Ọlọrun yoo fun oun ni ọmọ. Iwọ naa le fi ojú ẹmi wo o pe, lẹyin ọpọ ọdun ti o ti fi duro, irú àye ti ifẹ ọmọ yii yoo kó ninu ọkàn baba rẹ; ati ni pataki bi o ti jẹ pe ninu ọmọde yii ni ileri ti Ọlọrun ṣe fun Abrahamu rọ̀ mọ pe ninu Isaaki ni a o ti pe irú-ọmọ oun. Ileri naa niyẹn, ṣugbọn boya eyi jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ohun iyanu wọnni ti òye rẹ kò yé Abrahamu. Sibẹ naa, a kò ri kà pe Abrahamu bá Ọlọrun jiyàn, tabi o fa sẹyin ninu ohun ti Ọlọrun paṣẹ fun un lati ṣe, tabi o bá ara ati ẹjẹ sọrọ̀ nipa ọrọ naa. Bi o ba jẹ pe o ba ẹni kan sọ̀rọ nipa rẹ, lai si aniani wọn i ba ti fun un ni imọran bayii pe, "Ọlọrun kò beere iru ohun bẹẹ

lọwọ rẹ, maṣe dán an wo."  Ṣugbọn Ọlọrun n beere rẹ̀; Abrahamu si dide ni kutukutu owurọ lati lọ ṣe ohun ti Ọlọrun paṣẹ fun un lati ṣe.  Fun ọjọ mẹta ni Abrahamu fi n rin lọ si ibi ti Ọlọrun ti pe e.

**Igbagbọ́ ti Ki I Ṣe Nipa Riri**

Eyi ki i ṣe igba ayọ̀ tabi idunnu fun Abrahamu; o jẹ́ igba ironu ati idorikodo.  Ọlọrun n yiiri Abrahamu wò.  O ti fi ohun gbogbo rubọ ati Isaaki pẹlu.  Nisisiyii a n beere lọwọ Abrahamu boya yoo le fi Isaaki sori pẹpẹ tabi ki o mu un kuro.  Ṣugbọn Abrahamu fẹran Ọlọrun, o si fi Ọlọrun ṣaaju -- bẹẹ ni, ani ṣaaju ọmọ rẹ̀ ti Ọlọrun fi fun un.  Nigba miiran, awọn eniyan a maa sọ̀rọ bayii pe "Ni tootọ Ọlọrun ti fun mi ni eyi tabi eyi ni" Jobu wi pe: "OLUWA fifunni OLUWA si gbà lọ, ibukun li orukọ OLUWA."  Ọlọrun le fẹ ifararubọ ti o jinlẹ ju bẹẹ lọ ni igbesi-ayé rẹ.

"Ni ijọ kẹta Abrahamu si gbé oju rẹ soke, o ri ibẹ̀ na li okere.  Abrahamu si wi fun awọn ọdọmọkunrin rẹ̀, pe, Ẹnyin joko nihin pẹlu kẹtẹkẹtẹ; ati emi ati ọmọ yi yio lọ si ọhun ni, a o si gbadura, a o si tun pada tọ̀ nyin wá."  Igbagbọ́ ti Abrahamu ni ninu Ọlọrun ni o fi le sọ iru ọ̀rọ yii.  A sọ fun wa ninu Iwe Heberu pe nipa igbagbọ́ Abrahamu fi Isaaki rubọ, o si pari rẹ̀ si pe Ọlọrun tilẹ le gbe e dide.  O ni idaniloju pe Ọlọrun yoo mu ileri Rẹ̀ ṣẹ.  Bi o tilẹ jẹ pe oun mu aṣẹ Oluwa ṣẹ ti oun si fi ọmọ naa rubọ, Ọlọrun yoo gbé ọmọ naa dide kuro ninu okú.

Pẹlu igi ti a gbé ru Isaaki, ati iná ati ọbẹ lọwọ, Abrahamu mu ọ̀na rẹ̀ pọ̀n lọ si ori oke nibi ti Ọlọrun paṣẹ fun un lati lọ.  Ni oju ọ̀na Isaaki beerè ibeere yii, "Baba mi: … Wò iná on igi; ṣugbọn nibo li ọdọ-agutan ẹbọ sisun na gbé wà?"  Pẹlu iwuwo ọ̀rọ yii ni ipamọ ni ookan-àya rẹ̀, Abrahamu dahun bayii pe, "Ọmọ mi, Ọlọrun tikalarẹ̀ ni yio pèse ọdọ-agutan fun ẹbọ sisun."

**A fi Apẹẹrẹ Kalfari Hàn**

"Nwọn si de ibiti Ọlọrun ti wi fun u; Abrahamu si tẹ́ pẹpẹ kan nibẹ̀, o si to igi rere, o si di Isaaki ọmọ rẹ̀, o si dá a dubulẹ li ori pẹpẹ lori igi naa.  Abrahamu si nawọ rẹ̀, o si mu ọbẹ na.   "  O gbọ́ ohùn Oluwa ti o n wi bayii pe "Abrahamu, Abrahamu."  A dán igbagbọ́ wò, igbagbọ́ si yeje.

Ohun ti o hàn kedere fun gbogbo eniyan lati mọ̀ ni pe nihin Abrahamu n la idanwo ti o koro jù lọ ni igbesi-ayé rẹ̀ kọja ni fifi ọmọ rẹ̀ rubọ, ani ọmọ rẹ̀ kan ṣoṣo, ti o fẹ́, ni itẹriba burúburú -- ti ẹbọ sisun jẹ́ apẹẹrẹ rẹ̀.  Ṣugbọn irin-ajo lọ si Ori Oke Moria ju iyiiriwo ti o de ba Abrahamu lọ.  Ileri ti Ọlọrun ṣe fun Abrahamu, eyi ti a fi idi rẹ̀ mulẹ ni ọpọlọpọ igba ninu Bibeli pe, "ninu rẹ li a o ti bukun fun gbogbo idile aiye" n tọka si bibọ̀ Messia ati Ihinrere ti yoo mu wá si ayé.

Ileri Ọlọrun lati bukun fun Abrahamu ati lati sọ ọ di ẹni ibukun, eyi ti o duro le igbọran rẹ̀ si aṣẹ Ọlọrun pe ki o jade kuro ni ilẹ rẹ̀ ati kuro lọdọ awọn ará rẹ̀ ati ile baba rẹ̀ (Gẹnẹsisi 12:1-3, 7), ni a fi idi rẹ̀ mulẹ nigba ti o fi ọlá fun Ọlọrun nipa yiyẹra fun ija ati nipa fifi aimọ-ti-ara-ẹni nikan gbà fun Lọti, lati kọ́ yàn nigba ti wọn pinya (Gẹnẹsisi 13:14-17).  Ọlọrun tun fi idi ileri yii mulẹ nigba ti Abahamu fi ifẹ lati bu ọla fun Ọlọrun hàn ju ati gba ère fun ara rẹ̀ (Gẹnẹsisi 15:5, 7, 18-21); a tun fi i mulẹ nigba ti o fi tinutinu pa aṣẹ Ọlọrun mọ́ ti o wi bayii pe, "Ma rin niwaju mi, ki iwọ ki o si pé" (Gẹnẹsisi 17:4-8, 19).  Ni ipari, ni akoko ti Abrahamu fi Isaaki rubọ, Ọlọrun fi ibura fi idi ileri naa mulẹ, pe, "Emi tikalami ni mo fi bura, …pe, ni bibukún emi o bukún fun ọ … nitori ti iwọ ti gbà ohùn mi gbọ́" (Gẹnẹsisi 22:16-18).  Wo ibukun ainiwọn ti Abrahamu jẹ́ fun gbogbo agbaye nitori o gbọran si Ọlọrun lẹnu!

Ibi Isaaki, ọmọ ileri, jẹ ipilẹṣẹ imuṣẹ ileri bibọ̀ Kristi – "Ninu rẹ li a o ti bukun fun gbogbo idile aiye." Nigba ti a si mu Isaaki lọ sori Oke Moria lati fi i rubọ, o jẹ́ apẹẹrẹ "Ọdọ-agutan Ọlọrun" lori Oke Kalfari. Yiyọọda ti Abrahamu yọọda Isaaki jẹ́ apẹẹrẹ irubọ ti Ọlọrun ṣe ni yiyọọda Ọmọ Rẹ̀ kan ṣoṣo.  "Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bibi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun" (Johannu 3:16).

Ohùn ti o fọ̀ lati Ọrun dá ọmọ Abrahamu silẹ, a si fi ohun miiran rọpo Isaaki; ṣugbọn pẹlu ẹru igi agbelebu ni ẹ̀yin Rẹ̀ ni Ọdọ-Agutan Ọlọrun lọ si Kalfari.  A kò fi ẹlomiran rọpo, nitori ko si ẹlomiran ti o le ṣetutu fun ẹ̀ṣẹ wa.  Ọrun ṣokunkun, ayé si wariri, ṣugbọn ko si ohùn ti o fọ̀ lati oke wá, nitori Ọlọrun "kò da Ọmọ on tikararẹ̀ si, ṣugbọn ti o jọwọ rẹ̀ lọwọ fun gbogbo wa" (Romu 8:32).

**Iṣẹ-Isin Wa ti o Tọ̀na**

Ko si ohun kan ti Onigbagbọ́ le fi fun Ọlọrun, ti a le fi wé Ẹbun ti Ọlọrun fi fun araye; ṣugbọn fun imoore ifẹ ti Ọlọrun fi hàn si wa, Ọlọrun fẹ ki a fi gbogbo ọkàn wa fẹ́ Oun.  "Nitorina mo fi iyọ́nu Ọlọrun bẹ̀

nyin, ará, ki ẹnyin ki o fi ara nyin fun Ọlọrun li ẹbọ ãye, mimọ́, itẹwọgbà, eyi ni iṣẹ-isìn nyin ti o tọ̀na" (Romu 12:1). Ifararubọ ko i ti pe nigba ti a ba fi ọmọ wa ọkunrin, ọmọ wa obinrin ati idile wa rubọ, nitori Ọlọrun fẹ ki a fi ara wa fun Oun – ni ẹbọ aaye – fifi ara wa rubọ tabi yiyọọda ara wa patapata fun Ọlọrun lojoojumọ.

Paulu wi pe, "Emi npọn ara mi loju" (1 Kọrinti 9:27). Itumọ rẹ̀ ni pe, emi n pa ara mi lara, mo n mu un wa si itẹriba ki Kristi le jẹ ohun gbogbo ninu ohun gbogbo. Jesu mọ ọkàn eniyan nigba ti o wi pe, "Bi ẹnikan ba tọ̀ mi wá, ti ko si korira … ẹmí ara rẹ̀ pẹlu, kò le ṣe ọmọ-ẹhin mi" (Luku 14:26). Ọpọlọpọ n kunà nitori ifẹ kan wà ninu ọkàn wọn fun ohun kan, lati ṣe ohun kan tabi lati ni ohun kan, ti o le yẹ fun wọn ṣugbọn ti ko ni ere. Ni iru akoko bẹẹ o le wi pe, "Bẹẹ kọ́, emi ki yoo ni ohun yii bi o tilẹ jẹ pe Ọrọ Ọlọrun ko lodi si i, bi o tilẹ jẹ pe o tọ si mi, nitori mo fẹ mu ara mi wa si itẹriba; mo fẹ fi hàn pe nipa oore-ọfẹ Ọlọrun mo ni agbara lori ara mi." Ọpọlọpọ ni ko lero lati fi ohunkohun du ara wọn, sibẹ nipa fifi ohun keekeekee wọnni du ara wa ni ọna idaniloju lati bá Ọlọrun rin.

Ẹ ma ṣe jẹ ki a joko ti agbelebu wa, tabi ki a jẹ ki ẹlomiran ba wa gbe e, ṣugbọn ẹ jẹ ki a gbé agbelebu wa ki a si tẹle Jesu. Ẹ ma ṣe jẹ ki a fa iṣura iyebiye ọkàn wa sẹyin kuro lọdọ Ọlọrun, ṣugbọn ki a ni igbọran pipé si gbogbo aṣẹ Rẹ̀ ninu ohun gbogbo, lọjọọjọ, nipa bayii ki a le jẹ́ orisun ibukun fun awọn ẹlomiran.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni awọn eredi pataki kan ti o le mu ki o ṣoro fun Abrahamu lati pa aṣẹ Ọlọrun mọ nipa ọmọ rẹ̀?

2 Ki ni awọn ohun miiran ti o ṣẹlẹ ni Oke Moria nibi ti a dari Abrahamu si?

3 Nigba ti Abrahamu fi aṣẹ fun awọn ọmọ-ọdọ rẹ meji lati duro titi oun ati ọmọ rẹ̀ yoo fi pada dé, ki ni ṣe ti o fi lero pe awọn mejeeji yoo pada bọ̀?

4 Ipa wo ni Isaaki kó ninu imuṣẹ ileri ti a ṣe fun Abrahamu nigba ti Ọlọrun pe e jade kuro ni Harani?

5 Ọna wo ni Isaaki fi jẹ́ apẹẹrẹ Kristi nigba ti Abrahamu da a dubulẹ lori pẹpẹ bi ọrẹ-ẹbọ sisun?

6 Ki ni jẹ́ asọtẹlẹ ninu idahun Abrahamu si ibeere ọmọ rẹ̀ pe, "Ọlọrun tikalarẹ̀ ni yio pese ọdọ-agutan"?

7 Iwa-bi-Ọlọrun wo ni Abrahamu fi hàn nigba ti o mu ọmọ rẹ̀ lọ ni ìrin-ajo ọjọ mẹta si Oke Moria?

8 Iru iwa rere nla mẹta wo ni iwọ le ṣe akiyesi ninu igbesi-ayé Abrahamu lori ilẹ ayé?

9 Bawo ni iṣe Abrahamu ṣe fa imuṣẹ ileri Ọlọrun wá ti o wi pe "ninu rẹ li a o bukun fun gbogbo idile aiye"?